CRASH-19

# ÀLÀYÉ LÓRÍ ṢÍṢE AṢOJÚ-ẸNI LÁBẸ́ ÒFIN BÍ I TI ARA-ẸNI TÀBÍ BÍ I TI AKỌ́ṢẸ́MỌṢẸ́

## Kínni ṣíṣe aṣojú-ẹni lábẹ́ òfin?

Ní ti kí a sọ àwọn àyẹ̀wò ìṣègùn, àwọn òfin kan n ṣiṣẹ́ ní pàtó láti dáàbò bo àwọn ẹ̀tọ́ àwọn ènìyàn tí kò lè ṣe ìpinnu fúnra wọn. Lára èyí ni àwọn gbèndéke fún ṣíṣe ìwádìí ìjìnlẹ̀ tí ó kan àwọn ènìyàn tí ó lè, fún ìgbà díẹ̀ tàbí fún ìgbà pípẹ́, má lè fi ara mọ́ nnkan nítorí ìṣòro ìṣègùn kan, fún àpẹẹrẹ nítorí àìsàn tí ó le, àìmọra, ìṣòro nípa ìkẹ́kọ̀ọ́, ìfarapa ti orí tàbí àwọn ìṣòro ìlera ọpọlọ. Ní pàápàá, àwọn ìlànà àyẹ̀wò ìṣègùn nílò pé kí ẹni tí kò lè fi ara mọ́ ọ tó lọ́wọ́ nínú àyẹ̀wò, a gbọ́dọ̀ ti dá ẹlòmíràn tí ó yẹ mọ̀ tí ó lè fi ara mọ́ fífi orúkọ wọn sílẹ̀ fún àyẹ̀wò náà, gẹ́gẹ́ bí ṣíṣe aṣojú-ẹni lábẹ́ òfin.

A ti fún ọ ní ìfitónilétí yìí nítorí pé ikọ̀ olùwádìí náà ti dá ọ mọ̀ gẹ́gẹ́ bí ẹni tí ó yẹ láti ṣe aṣojú-ẹni lábẹ́ òfin. Awẹ́ ìwé yìí àti awẹ́ ìwé ìfitónilétí olùkópa tí ó tẹ̀lé e yóò ṣàlàyé ohun tí ìwádìí yìí fi kan ìwọ àti agbàwòsàn náà.

## Kí ló dé tí a fi wá bá mi?

Aṣojú-ẹni lábẹ́ òfin lè jẹ́ ẹnìkan tí ó ní ìbáṣepọ̀ pẹ̀lú agbàwòsàn náà ṣùgbọ́n tí kò ní ìfẹ́ inú tí ó lòdì, bíi kíkópa nínú iṣẹ́ ìwádìí náà tàbí jíjẹ ànfààní owó. Àpẹẹrẹ àwọn ènìyàn tí ó yẹ tí ó lè ṣe irú iṣẹ́ yìí ni:

- Mọ̀lẹ́bí, olùtọ́jú tàbí ọ̀rẹ́ kan
- Atẹ̀lé kan tí ilé ẹjọ́ yàn tí ó ní ìbáṣepọ̀ ara ẹni pẹ̀lú olùkópa náà

Nígbà tí a bá ti gbé àwọn ìgbésẹ̀ tí ó jọjú láti dá aṣojú ara ẹni lábẹ́ òfin mọ̀ tí kò sì sí ìkankan, nígbà náà ní òṣìṣẹ́ àyẹ̀wò náà gbọ́dọ̀ yan ẹnìkan láti ṣe aṣojú agbàwòsàn náà. Ẹni yìí lè lọ́wọ́ nínú ìtọ́jú agbàwòsàn náà ní ipò akọ́ṣẹ́mọṣẹ́ ṣùgbọ́n kò gbọ́dọ̀ ní ìbáṣepọ̀ pẹ̀lú iṣẹ́ ìwádìí náà. Ẹnìkan tí ó yẹ lè ṣe ojúṣe akọ́ṣẹ́mọṣẹ́ aṣojú-ẹni lábẹ́ òfin jẹ́ oníṣègùn tó dá ṣiṣẹ́, tí ó nṣiṣẹ́ pẹ̀lú agbàwòsàn náà tàbí ẹni tí olùpèsè ìtọ́jú ìlera náà bá yàn.

## Kínni àwọn Ojúṣe Aṣojú-ẹni lábẹ́ Òfin?

Ojúlówó ojúṣe aṣojú-ẹni lábẹ́ òfin ni láti fi ara mọ́ ọ pé kí ìwádìí yìí kan agbàwòsàn náà. Fífi ara mọ́ náà kò pọn dandan, tí o kò bá sì pèsè èyí a ó ka ìpinnu rẹ sí.

Láti lè ṣe ìrànlọ́wọ́ fún ọ láti ṣe ìpinnu nípa ṣíṣe ojúṣe aṣojú-ẹni lábẹ́ òfin, kí a sì lè rán ọ́ lọ́wọ́ ní ṣíṣe ìpinnu nípa ṣíṣe ojúṣe aṣojú-ẹni lábẹ́ òfin, àti láti ṣe ìrànlọ́wọ́ fún ọ láti pinnu bóyá ìwọ yóò fi ara mọ́ ọ, awẹ́ ìwé míràn nìpa ìfitónilétí olùkópa náà njúwe ohun tí àyẹ̀wò náà rọ̀ mọ́. Ìfitónilétí yìí jẹ́ ọ̀kan náà pẹ̀lú èyí tí a fifún àwọn agbàwòsàn tí wọ́n lè fúnra wọn ṣe ìpinnu.

## Kínni yóò ṣẹlẹ̀ tí mo bá fi ara mọ́ ọ?

Tí o bá fi ara mọ́ ọ fún ọ̀rẹ́ tàbí mọ̀lẹ́bí rẹ láti kópa nínú àyẹ̀wò náà a jẹ́ wípe òun jẹ́ olùkópa ní kíkún. Awẹ́ ìwé ìfitónilétí náà, tí olùwádìí yóò ṣàlàyé rẹ̀ fún ọ, ni ó njúwe ohun tí èyí yóò kàn. Tí o bá fi ara mọ́ ọ nísisìyí o lè yọwọ́ ìfaramọ́ rẹ kúrò nígbà kúùgbà lọ́jọ́ iwájú. Tí ọ̀rẹ́ tàbí mọ̀lẹ́bí rẹ bá bá tún ní okun nígbòòṣe, a ó béèrè lọ́wọ́ rẹ̀ bóyá òun yóò nífẹ̀ẹ́ láti tẹ̀ síwájú ní kíkópa nínú àyẹ̀wò náà.